Chief Secretary to the Government

# EKO AKETE.

"Emi yio fi ohun ti o ndun Makunnu han awon Alagbara, Ngo si je Alagbawi awon Odi."—W. T. Stead.

Vol. II. No. 88. SATURDAY, MARCH 15, 1924. Fourpence.

**DURO THOMAS.** 18 MAR 1924

55, MASSEY STREET, LAGOS, (NIGERIA.)

P.O. Box 374. Telephone No. 243.

*The Best House for every Description of German Goods.*

**"Specialities: Enamelware Beer, Wine, Iron Bedsteads, Ruby Plates, Rubber Beads of all kinds, Clay and Briar Pipes, Champagne, Cement, Biscuits in cases, Gun Powder, Wire Nails Raugoon and original Ballam Rice, Accordeons, Piano, Padlocks, Beads, etc., etc., etc."**

N. V. HANDLEMATTSCHAPPIJ V.H.

**J. F. SICK** ati AWỌN ẸGBẸ.

No. 7, Ita Ibode laiki, l'eti *Glover Memorial Hall*, (*Customs Street*,) EKO.





Awọn Oyinbo Onișowo yi nranșẹ MASINI-ARANSO ti a npe ni VESTA Nos. 1-4 t' ọlwọ ati t' ẹlẹsẹ ni owo to rọju, a le fi iye-owo wọn han ẹnikẹni to ba lọ si Ile-owo yi.

Nwọn mura tan lati șe adehun pataki pẹlu ẹnikẹni to ba fẹ ransẹ Mejila tabi jubẹ lọ ninu MASINI na.

Awọn Oyinbo yi nșe orișirisi Ilẹkẹ alarabara, nwọn si nranșẹ *Cement* ati panu kikọle to nipọn, ati ẹja abọmafọ ati orișirisi ọja.

Ilẹkun Ile awọn Oyinbo yi și nigbakugba ti enia ba fẹ lati lọ ba wọn sọrọ ASIRI nipa OWO. IROHIN KO TO AFOJUBA.

**J. C. VAUGHAN**

Ti Ile-Ọja Sheffield ni Ita Kakawa ati Ile-Ọja "*Excelsior*" ni Ita Agarawu, ni oniruru awọn ohun elo ikọle fun tita ni owo ọpọku-ọyọku.

O ti nṣowo Irin Iṣẹ lorişirişi lati adọta ọdun sẹhin titi di oni.

ATARI AJANAKU ni ỌGBẸNI na jẹ ninu awọn onişowo Irin Iṣẹ ni ilu Nigeria.

ỌKỌ tita wa ni owo pọ o.

**B. O. Joseph**

*Commission Agent.*

21 years experience in trade.

Cotton.

Sundries.

Hardware.

Provisions.

27, Koseh Street, Lagos.

Cable Address:—
"Steinafrik" HAMBURG.

**E. H. STEIN & Co.**

HAMBURG, Neurwall 16/18,
Hildebrandhaus.
*AFRICAN MERCHANTS.*

***ALL INDENTS EXECUTED.***

for
English and Continental Goods
and
PRODUCE
Sold on Best Terms.

**Produce to Europe covered by Floating Marine Insurance Policy.**

*P. O. Box No. 505.*

Agent in Lagos:—

**Mr. Karimu Kotun**

Broad Street, & Portonovo Market Store.

ẸNIKẸJI,

Aşọ Oke to yanju mbẹ lọdọ Iya Afin Saamọta Ikẹ Ọlọrun fun tita, ọpọku Ọyọku ni owo wọn, lọ bere ni 3 St. John Street, l'Eko, leti ile Johnson Agbẹjọro.

# BULL WEST AFRICAN LINE, INC.

AWỌN ỌLỌKỌ TI IJỌBA AMẸRIKA

Ọkọ elefi awọn Oyinbo wọnyi nko ero ati ẹru ni Iwọ Orun Afrika, ni oşoşu o si ngba ero lọ si ilu Amẹrika ati awọn ilu miran pẹlu. Ọkọ wọn yara, owo pọ ni nwọn si ngba Ẹnyin ero, ẹnyin onişowo Obi, Koko, Ekuro ati Epo, ẹ lọ ke si aşoju awọn Ọlọkọ yi ni :— Oke Pẹtẹsi ile *Colonial Bank*, ni Ẹhin Igbẹti, Eko.

# ERO YA WA RA.

ADEBOYE ŞOLANKẸ Onişowo "Gbabiọgẹdẹ" ni Panu-kikọle ati kikan-ọkọ Işo lorişirişi, Kọkọrọ (Işika) t'ilẹkun ati t'apoti lorişirişi, Atupa fifalọwọ, Simẹnti, Ọda lorişirişi ati Epo-ọda, Fikifiki, Okun-ẹrọ, ati Ọşan, ati Pakun ti Awo-ẹja lorişirişi, Awo awọn Aganyin fi nko Ẹja-şawa l'okun ati Ẹja Abọmafọ, ni Ile-ọja rẹ ni No. Idunmagbo Street, (l'ebute Olowu) ati ni No. 19, Moloney Bridge Street (l'Anikantamọ) l'Eko.

O nta Iworo (Golu) ati Fadaka-tutu ati Irin-işẹ Agbẹdẹ Iworo ati Fadaka.

OWO ỌJA RẸ FANIMỌRA.

Ẹ LỌ RA TIYIN NIBẸ.

*Editor & Proprietor*:—
ADEOYE DENIGA,
*Offices*: 22 & 24, Williams Street,
P.O. Box 286,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Odun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.

## GBOHUN-GBOHUN.

IYA OLOGUN DUDU INU ADO, AWO NYIN YA!

Ori lo yọ Ọgbẹni Y. A. Oseni ti Ita *Evans* ni *Saturday* to kọja nigbati ọmọde-kọnrin kan lọ da ọgun ẹtẹ si'le rẹ ti o si ni on wa ra panu nibẹ nigbati Ọgbẹni onile na ra mu; nigbẹhin-gbẹhin ọmọ yi jẹwọ pe iya on to ngbe apa Oke Oṣodi mọ Araọmi lo ran on lọ ṣe jamba na, ṣugbọn ewe ti sun'ko nigbati ariwo ọrọ na ti sọ lala; ẹnyin iya-ki'ya, ẹ ṣọra ebu ika ti ẹ ngbin, ki o ma ba hu sori ọmọ nyin bo d'ọla.

ẸGBẸ TUNLUṢE DARABA T'APA ỌMỌDE KO KA.

Awọn Ẹgbẹ Tunluṣe ṣe Aragbabu Ipade wọn ni Satide to kọja. Ọgbẹni Herbert Macaulay si sọ kasi-nkan ọrọ lori ọrọlọpọ nkan; awọn Ọmọ Ẹgbẹ le ni Ẹgbẹrindilogun (3,351) Oluwa Oloye lo ṣe Alakoso Ipade, ati Ọgbẹni Majọlagbe Asọgbọn. Ọgbẹni J. Bagan Benjamin Akọwe Ẹgbẹ, ka ohun ti Ẹgbẹ ti ṣe sẹhin Alufa Ijaoye si gba gbogbo rẹ sọ. Ipade tuka ni agogo meje-abọ alẹ.

PA SAWYERR, O DI GBERE!

Tẹdun-tẹdun la fi kede ti'ẹ'rigba'ṣọ Ọgbẹni wa S. J. Sawyerr ni ọsẹ yi, a ba awọn ẹbi rẹ daro ọfọ yi, ẹ ku afẹku.

AWỌN OGUNNA-GBO-NGBO CHURCH C.M.S. MA WARIKO ṢE AJỌWO.

A gbọ pe *Bishop* Eko, *Bishop* Howells, Ọgbẹni Henry Carr Am fin ti *Church* Eko, Ọgbẹni Ajasa Ọlọla, Amofin ti *Church* Odo Ọya yio jọ jiroro pọ lori ọfin *Church* Odo Ọya lai pẹ.

ẸJỌ IMALE NI GANRAN.

Tọtun-tosi ti bu ẹjọ ro, o ku ki Adajọ da ṣẹria; lẹhinna a o sọrọ lori ẹjọ tian-tian yi.

O ṢEUN IWỌ ỌMỌ ỌDỌ RERE.

Awọn Agbagba Iya Afin diẹ ti *Church Wesley* ni Ita Tinubu, awọn jakanjakan bi Mrs Emily Cole, Mrs. Berkeley, Mrs. Mary Marsh, Mrs. Macaulay, Mrs. Lindsey ta Ọgbẹni Simeon Johnson ti 4, *Chapel Street* Olowogbowo lọrẹ Bibeli kan tun imọ iyi iṣẹ rẹ bi Ọiju Ijọ na ti o ti nṣe ni *Church* yi lati ọdun kẹwa. Aṣalẹ *Wednesday* ọsẹ yi ni a ṣe iyẹsi na; awọn ọkọnrin diẹ ti ninu wọn jẹ *Member Church* na ran awọn Iya wa wọnyi lọwọ ninu iṣẹ rere yi. A gbọ pe Iya Afin Mrs Marsh lo da imọran na, ti awọn Ẹgbẹ rẹ si fi tọkan-tọkan gba.

Ọṣuṣu nyin niyi o! Ẹnyin Iya to mọ iyi to m'ẹyẹ.

SIMONI ỌMỌ JONAH, IWỌ FẸ MI?

A ṣọpẹ lọwọ Ọgbẹni E. Bar Jona—Claudius Thompson ti Ile Ọwọ awọn Oyinbo *Humtley* ati *Bentley* fun ọrẹ ṣile mẹwa to fa wa ni lọlọ yi; ọwọ a r'oke o!

ỌBA MẸWA IGBA MẸWA.

Alufa Latunde, Oloye B.A. yio de si'lẹ yi lọ-ẹ to mbọ. awọn aliṣẹ *Church* C.M.S. yio si ṣe a-kẹkẹ fifi si Ijọ St. Peter ni *Sunday* ọsẹ to mbọ. Ẹnyin *Member Church* Alapako, Ẹ ku a-foju-s'ọna.

ZANU, SERIKI!

Ọba Ilu *Katsina* ti Ilẹ Hausa de sibi l'ọsẹ yi lati wa sin Gomina Agba ẹniti o lọ si lu Ọba ni ana. *Zaiki, Seriki, Nna Gidu?* (ile nkọ.)

OLORI LA NFORI FUN.

Ni ijẹta Kotu fi Ọgbẹni Ephraim Conrad Taiwo ọmọ Ijoye Taiwo Olowo (Ologbe) jẹ olori Ile Baba rẹ nipa fifun ni gbogbo kọkọrọ Ile na ti o wa ni Ita Taiwo. A gbọ pe o nna awọn Ẹbi Ijoye Taiwo Olowo na ni ọgọfa pọun (£120) lati fi tun gbogbo Ile na ṣe. Eyi wu wa o. Ẹnyin Iya wa, Layide Taiwo, ati Fiyakọla Taiwo, ẹhin baba a dara o!

---

Awọn orin ti Alli Mabinu fi ṣe ariya fun Olulana ni Ko-ni-gbagbe Monday.

(BY ADE: OLA; AJIB.)

Ohun Orin:—*Ara Oke o, Ẹnyin lo sọ gari etc.*

Sec. II T'ewe t'agba o, kẹ wa ba mi k'Iṣọla o.
(*twice*)
K'ẹ wa ba mi ki Iṣọla o, Ọrẹ mi,
Ka mura ka, ka mura ka jọ yọ; Baba wa lo de,
Ọrẹ mi, ka mura ka jọ yọ, baba wa lo de.

Ohun Orin:—*Ko ni ṣẹ l'apa o,* (Awori)

III Araiye ẹ wa o, Iṣọla ma to baba fun gbogbo ọṣẹsin, (*twice*)
Ka s'ẹsin ni'ṣe ẹtọ o, ẹ jare! lọwọ rẹ lo pẹkun si o; ara la mọ, a o mọ'nu o,
(*twice*)
Araiye! ẹ wa o, Iṣọla ma to baba fun gbogbo enia.

Ohun Orin:—*O f'ori yagba lọ ki wọn.*

IV Brọdahudu ni ka ṣe o, (*twice*)
Isin ẹtọ, oniye! isin ẹtọ ni nwọn gbe kale.
T'ọmọde t'agba kẹ mura, Brọdahudu ni ka ṣe o.

Emi o ba'Ṣọla sa lọ o (*twice*)
Ara ilu, oniye! ara ilu kẹ sọ f'ọba o,
Owẹli (*Owen*) yẹn, dakun, emi o ba' Ṣọla salọ o.

V Brọdahudu ni ka ṣe (*twice*)
Ẹnyin Bẹtẹli (*Bethel*) ẹ sare wa,
T'ọmọde t'agba ẹ sare wa o,

---

**Thanks for Sympathy.**

Messrs A. O. and B. A. Cole, T. A. Bankọle and family hereby return their thanks to those who sympathized with them during the recent bereavement which befell them by the sudden death of their beloved VICTOR O. BANKỌLE.

ILE-ÒWÒ OYINBO ALALUMỌGAJI

# John Holt

NI OJA WỌNYI FUN TITA

Sarotu "Alasia"
Keke-ologere (Elerin)
Keke-Ologere
(*Rudge Whit-Worth*)
Panu Iborule
Awo
Awo-abomafo
Eja-abomafo
Iyefun
Sulfuri
Efun
Alum
Oda-dudu
Orisirisi Oda-ikunle
Iso
Panu-kiko'le
Isana (Atuko)

Ẹ bere ni Ṣabu JOHN HOLT ni Opopo-nla, ni Eko.

"*Ebani*" ni ede-waya ti ẹnikẹni le lẹ si wọn nibikibi ni Eko tabi ni Ilu miran ni *Nigeria*.

## FACTS AND FIGURES

### AN ORDER OF THE COURT.

The Mohammedan religion came to us from the North where primitive and Oriental customs prevailed. For this it is generally conceived that all Oriental and native practices are endorsed by that religion. But the fact that Islam is making headways in England, France, Germany and many other European countries as well as the United States of America is a direct negation of this idea. In these days of enlightenment when Mohammedans in Lagos begin to move rapidly forward in Occidental education and civilisation it becomes clearer than ever that Islam is as universal as Christianity and can be adapted to any custom or civilisation.

In view of the above facts it is as surprising as it is degrading to notice that in accordance with an order a present in force in the Law Courts Mohammedans must taket off their shoes when giving evidence. The writer was in court the other day when a youngman of this town (Mohammedan by faith) who was accustomed to European dress was engaged in a civil action. To the surprise and indignation of all present he was ordered to take off his shoes ! ! !

Is it against the law that the Mohammedan subjects of His Majesty the King should adopt European custom as the Christians do? What justification on earth can the authorities concerned give to this highly degrading order-in-court? Is it that the Mohammedan religion supports it or that a section of the Mohammedans are accustomed to such practice? If the latter, why then should educated Muslims be forced to obey a custom which to them is primitive and disagreable to their mode of living? The reason, we are told, why such an order is passed is that Mohammedans are allowed to keep on their turbans in the Courts, they therefore should remove their shoes as they generally do before entering a house as a mark of respect. But this should not apply to all Muslims as turbans are not worn by all Muslims. A Mohammedan who is clad in European dress has to take off his straw hat for instance, and, for that particular individual to have to remove his shoes again baffles our understanding.

But this may not be the reason that brings about the enforcement of this order. Whatever the reason or reasons, may be it is bringing back the hands of the clock when a civilised and educated Muslim shall have to take off his shoes after taking off his hat before giving evidence in the Law Courts simply because the illiterate and primitive bulk of Mohammedans in Lagos are used to a certain custom.

However, we hope educated Muslims in Lagos will join hands together to petition the Government with a view to get the order repealed.

ADEKANBI.


**M. D. MARTINS**

23, SCALE SQUARE, LAGOS.

Ọgbẹni yi jẹ ẹniti o nṣe ọti orişirişi. Ginger Ale, Şile mẹta abọ (3/6) fun Doz. kan ninu Igo Beer, ati Şile mẹta (3/-) fun ẹniti o ba fẹ ra pupọ bi Dozen marun (5 Doz) ati ju bẹ lọ.

Lemonade bakanna, Cider Champagne bakanna Soder Water ninu Igo kaona Şile kan ati Nain (1/9)

O npọn ọti ni Jebba Street, Ebute Mẹta.


Ilu Awori
Igberiko Eko.

Si Oni'we-irohin "EKO KETE"

A dọbalẹ o,

Awọn Balẹ Balẹ Igbo Awori nfẹ ki Ijọba ati Igbimọ Ilu Eko ninu eyi ti awọn jẹ Igberiko wọn, yọda fun wọn lati tun ọna ilu şe ki Mọto ati Kẹkẹ ologere le ma wọ ilu wa. Mọto yio si ta ni ilu nwọnyi daradara, Mofoluku, Ejigbo, Mafọn, Idimu, Ikọtun, Ẹgando, Akẹsan, ati Işẹri-ọşun.

Ẹ o ri wabi-wọsi ẹru ko ni ilu nwọnyi.

Ẹ ba wa şe, "EKO AKETE" o di ọwọ rẹ o.

A tumba o!
ARỌBADADE.

## WARNING.

On the night of 10th February, 1924, thieves entered into my dwelling house at No. 27, Ọbadina Street, Lagos, and amongst those things stolen away, was a document for a house at Accra, Gold Coast, belonging to Late Madam Sadatu, Iya Kolobo, purchased from Danjinba—Title Deeds—Registered No. 1218/97 of 3rd July, 1897.

If this Title Deed is presented to any one in Lagos or at Accra, for purposes of raising loan—please note that it is a stolen document.

HIS
TAIRU X ADIGUN.
MARK


**A. B. Bakare**

AKUN ILE L'ỌDA

jẹ ẹniti o nkun Ile lorişirişi awọ ti ẹ ba fẹ o si mọ Ọşọ Ile şe pẹlu. O ti nşe işẹ yi le ni ọpọlọpọ ọdun sẹhin lọdọ awọn Oyinbo ara Germany kan ti a npe ni Ring and Starke.

Ọrẹ, Ẹ lọ ke si ni Ile rẹ ni :—

45, Forsythe Street,
Eko.

**EKO AKETE.**
EKO, SATURDAY, MARCH 15, 1924.

## ỌLỌPA "ẸRU" ILU, ABIṢOKOTO PỌNBE!

Ede "Ẹru" ti a lo fun awọn Ọpa-Ọba yi, kiṣe ti ẹru ti a f' owo ra; bikoṣe ti pe lati apo-owo Ilu ni a ti nsanwo fun wọn loṣoṣu: a lõ ni ede ifẹ gẹgẹ'i iyakọ aya ọkọnrin kan ti le ma pe aya ọkọnrin na ni "Ẹru mi;" lona na ni a lo ede yi bi igbati a gba ọrọ ti a nsọ layun.

Ki a wa bẹrẹ ohun ti a fẹ sọ wayi; kosi ẹniti ko gbọ jamba ti awọn Igara oju omi kan ṣe si awọn ara ilẹ yi kan bi nwọn ti nti ọja bọ nilọlọyi, nipa dida ibọn bo·wọn lagbami, tobẹ ti nwọn fi pa awọn enia diẹ, ti nwọn si ko ẹru wọn; irufẹ iwa yi fi han gbangba pe aisi ọlọpa to, ni apa Oriba tabi Ẹpẹ lo mu ki Aluba yi kọlu awọn enia na; nigbati a si ri Dr. Ṣapara lọsẹ tokọja lẹhin igbati o bọ wa le fun iṣẹ "*jijuri*" oku awọn enia na ti a pa lọna bayi, ti a bi pe o to ọlọpa mẹlọ ni Ijọba fi sibẹ? Ọgbẹni na dahun pe on ko ri ju bi mẹfa ti o nṣiṣẹ jakejado Igboro Ilu Ẹpẹ ati awọn ilu ṣọ̀lọ̀-ṣọ̀lọ̀-ṣọ̀lọ̀ bi Oriba, Langbasa ti nwọn nbẹ lagbegbe rẹ; eyi jẹ ohun ti o ku diẹ koto. Kini Ọlọpa mẹfa pere toṣe ninu iṣẹ tiantian ti o mbẹ ninu awọn Ilu wọnyi? Ẹnyin ẹ lọ wo Ikoyi nisinsinyi, ẹ o ri bi ọlọpa ti ja ibẹ jã, bi igbati iyọ ja ọbẹ. kilọ a ti ng' oku lọrun? O ha jẹ pe nitoriti a sọ ibi yi di "Ilu Oyinbo Kekere" l'aiin Eko, lo mu ki awọn Olori Ọlọpa dari ọgọrọ ọmọ-iṣẹ wọn sibẹ bẹ, ki awọn enia ibomiran mã rare a'rẹni tọju wọn ni? Tabi o ha jẹ pe awọn ara ilu miran ko fẹ itọju gẹgẹbi awọn Oyinbo ni?

Ti awọn olori Ọpa-Ọba ko ba tete jigiri lati fi awọn oniṣẹ ti o to sọjọ ki nwọn ma kakiri oju omi lọna Ẹjẹ lati ki awọn "Adeoṣun" wọnyi wọ̀ dajudaju ewu ṣi nbẹ sibẹ.

Irufẹ a nfi ibọn rẹ enia lagbami bayi, ṣe nwọpọ nisinsinyi, bẹni awọn kan fi ara gba lomi Langbasa lẹnu ọdun tokọja nigbati nwọn nmu ọja tita wọn bọ wa silẹ yi: ki a to sa fun ewu Iji, ki a tosa fun ewu Igara-dánàdánà loju omi, eyi ko ṣe "ngejia" ẹnikẹni bi?

Titi di isinsinyi a koi ti gbọ fẹnrẹn pe ọwọ ti ba awọn Apania-kẹru wọnyi; yio jẹ didun inu Ilu Ipọlọpọ ti ọwọ ba tẹ wọn: nitorina a tanma pe awọn Ọgbẹni wa R. B. Reis, A. Ọpẹnibo ki yio ṣai tọpasẹ wọn de i'ẹ-tẹ-ile-iku, ki ofin ba le bere ẹjẹ awọn alaiṣẹ-alairo ti nwọn ti ta silẹ lojiji yi lọwọ wọn.

Apa Ẹpẹ yi nikan kọ ni ibiti a gbọ pe awọn Idai fọ yi ndana, bẹni a sọ fun ni pe nwọn nṣe lọna Ọjọ; aṣa na ṣe "nbuaya," a si ro pe awọn Olori Ọpa Ọba ko ni f'aye silẹ ki arun yi ma gberansiwaju si.

Ṣugbọn ju gbogbo rẹ lọ, ọkan lo daniloju nibẹ, eyini ni pe ọjọ gbogbo ni t'ole, ọjọkan ti onilun ki ṣọ.

---

## STOP PRESS!!!

*On dit* that a high-placed official, is likely to retire soon: guess, reader, guess!!!

Sir Donald Cameron, K.B.E. sworn in, Acting Governor, yesterday in the Council Chamber with befitting ceremonials.

# ERVEN LUCAS BOLS

## AMSTERDAM

**1575**

Whenever you see the word

# BOLS

It means a reputation of over 300 years.

***Bols very old LIQUEUR GIN is the Gin for the man of good taste.***

**STONE JARS AND GLASS JARS**

**5s.** per Bottle

***FROM***

# GRACE BROS.

***— DRINK IT NEAT. —***

# ILE IFI ỌJA AWỌN ENIA PAMỌ SI LAILEWU.

Nigbati Ọja rẹ ba de lati Ilu Oyinbo, ti o si ni ẹ lara lati san owo Ibode lori awa yio ba ọ gba Ọja na, a o si ba ọ ṣe opo iwe gbigba wọn ni'bode.

Ti o ba si fẹ gba Ọja rẹ na lọwọ wa, iwọ maṣe ṣopo ati gba gbogbo wọn lẹ̀k, bikoṣe eyiti ipa rẹ ba kọkọ ka na lati sanwo 'bode fun.

Iwọ yio ri pe ọna yi na ẹ lẹhin ju pe ki o lọ t'ọrun bọ igbese lọ!

Ẽra ko ni ra Ọja rẹ na ti o wa ni itọju wa.

Abẹ abo Agbowo-ode Ọba ni ile Ifi oja awọn enia pamọ si lọdọ wa wà.

Igbakigba ti Ọja rẹ ba tun de, ti owo ba si pọ lọwọ rẹ lati gba wọn, sa lọ ri Ọgbẹni yi:

**JAMESON,**

Ni Opopo-nla,

Leti Ile Dr. O. Sapara, I.S.O

l'Eko.

## TANWIJI, YÀNMÙ-YÁNMÚ.

[ *Lati ọwọ* ATARI AJANAKU. ]

Si Oni 'we-irohin "EKO AKETE."

Mo bẹrẹ f'oji,

Orişirişi ọna ni awọn Munisipa (Municipal Department) fi ngba owo lọwọ Ilu, ka to san owo ile, ka to san owo omi, ka to fi owo ra kẹkẹ ologere (*Bicycle*) ka to tun fi owo ra yago-l'ọna, ninu igbe ko s'owo ko s'owo ti gbogbo ilu nke nisisiyi. Owo ko lọ dede mọ, ọpọlọpọ orişowo di ọnigbese, Oyinbo ndin owo ọja ku diẹdiẹ ni Şabu, Ijọba nda Akọwe duro, ile ti nwọn ti nhaya ri ni pọun mẹrin loşu di pọun meji abọ, pẹlu bi gbogbo nkan ti ndin owo ku diẹdiẹ yi, nitori ibajẹ owò sibẹ-sibẹ anu enia ko şe ọga awọn Oyinbo oke-odò, *General Manager Nigerian Railway*, lati din owo ọkọ *Railway* ku, ati owo ẹru wiwọn.

Nigba pupọ ni a nri awọn obinrin to nşe wahala lọ si Agege, Oşodi, Alagbado, ati ibomiran lati lọ şe owo pẹpẹpẹ nibẹ, şugbọn pẹlu gbogbo wahala wọnyi, melo ninu wọn lo le wọle ko jade nigbati inanwo pọnwun meji pere ba yọ si wọn lojiji? Iba ere diẹ kiun ti iba bọ si apo wọn, o ti ba owo ọkọ ati owo ẹru wiwọn lọ. Bi enia ra Obi lati fi ranşẹ si Kano, tabi Ororo-Ẹpa lati Kano wa si Eko fun tita, lẹhin ti oluwarẹ ba yọ owo to fi ra wọn kuro, to si yọ owo ọkọ ati owo wiwọn kuro, eyi to ku gbese ni. Njẹ, kini anfani *Railway* tabi ọkọ ilẹ ti ko şe ilu ni rere?

A si wadi soke, sodo, kini nwọn ti nşe gbogbo owo ti *Railway* ngba; a ri pe ọgọrọ ninu rẹ lo mba owo işẹ oşoşu awọn Oyinbo lọ, laika eyiti nwọn fi nsan owo ọkọ wọn lọ si ilu Oyinbo. O yẹ ki *Nigerian Railway*, mọ pe inakuna pọ nibi işẹ on, nigbati Colonel Hammond ba si jihin işẹ rẹ tan nilu Oyinbo ni lọlọyi, o da mi loju gbangba pe, ọpọlọpọ igi ti ko gba so eso rere ni *Railway*, l'a o ke lulẹ, ti a o si wọ sinu ina.

Bi *Nigerian Railway* ti şe eti gbọin s'ọde, ti nwọn si nşe agbẹran s'eşu yi, bẹni o dabi ẹnipe awọn Munisipa ko bikita lati din diẹ ku ninu orişirişi owo ti nwọn ngba lọwọ wa. Lati şile meji abọ, owo iwe (*license*) kẹkẹ ologere (*Bicycle*) fo fẹrẹ lọ di şile mẹwa lọdun, bi enia si fẹ lati pa Ewurẹ, Agutan tabi Malu jẹ nile rẹ, o ni iye owo ti o ma san fun awọn Munisipa ko to le dunbu rẹ. Lati le toju ilu bo ti tọ, ati bo ti yẹ daradara, Munisipa ni lati l'owo lọwọ: şugbọn anu şe ni pe wọn ko tun ilu şe to bi nwọn iba ti tun şe. Ti a ba yọ ọwọ opopo ọna Ẹhingbẹni, Ẹhin-ogba, Broad Street ati opopo miran ti Oyinbo ngba nigbakugba kuro, adugbo pupọ ni Ilu lo nfẹ itunşe ati itọju. A ko le şeşẹ ma darukọ gbogbo adugbo to nfẹ itunşe bayi, nitori ko si ibiti awọn Wole-wole (*Sanitary Inspectors*) ko mọ ninu gbogbo wọn.

Tanwiji to wa loju gọta (*gutter*) ita ẹlomiran ati eyiti o wa ninu adagun omi to rron ni'ta gbangba l'adugbo ẹlomiran ju ẹgbẹrun ọkẹ lọ. Awọn Wole-wole ko npe Ijọba tabi Munisipa l'ẹjọ nitori wọn; şugbọn jẹ ki nwọn şeşi ri ẹyọ Tanwiji kanşoşo pere ninu Ikoko Şẹba tabi ti Asinmọun, rẹrẹ, o di Kotu (*Court*) rẹrẹ. Dipo eyiti Oni-tajọ iba da şẹria Sisi tabi Şile kan fun wọn, a ni ki nwọn lọ san Şile marun, Şile meje abọ, Şile mẹwa bi ẹni wipe nwọn le fẹ Tanwiji tabi Yanmu-yanmu ku ni'le on papa.

Ẹda Ọlọrun ni Tanwiji ati Yanmu-yanmu jẹ; gbogbo Dokita Eko ati ti ilu Oyinbo ko si le le wọn kuro l'aiye. Nwọn ki nşe Orişa ti Enia Dudu le bọ, bẹni wọn ko nşe Cocoa tabi Ekurọ ti a le ta fun Oyinbo l'ẹhingbẹti; sibẹsibẹ, alalẹ ni a ngbọ orin aro wọn pẹlu ẹbẹ ati ijakadi lati wọ abẹ apo (*Mosquito Net*) ti a nsun si.

Orişirişi Tanwiji ti Oyinbo npe ni *Bacteria* tabi *Germs* lo pọ l'aiye gẹgẹ bi oniruru eweko igbẹ; şugbọn diẹ kinun ninu nwọn lo le şe enia ni jamba. Bi eyikeyi ninu awọn diẹ yi ba si wọ inu ara lati pọ oro sibẹ, ijakadi diẹ kinun kọ ni *White Corpuscles* tabi ẹ̀ẹ̀ funfun nba wọn ja lati pa oro wọn; şugbọn nigbati o ba şe, agbara ẹje yi yio ma din ku diẹ-diẹ, nitorina ni a şe ni lati ma wa ni mimọ ati li aileri nigbakugba, ka ma si şe jafara ati kesi Dokita lakoko aisan.

Şugbọn Dokita to ba wipe ko si eyiti o dara ninu gbogbo agbo, agunmu ati egbogi wa miran, o npurọ ni. Amuyó ati amuju laisi iwọn lo nba egbogi wa jẹ. Nitorina, yio jẹ ohun daradara fun awọn Dokita wa lati kọ egbogi ti ilẹ wa ni akọye; eweko igbẹ, irufẹ eyi ti a nta l'Ọbun Eko la fi şe ọpọlọpọ egbogi Oyinbo; eso lara ni a fi nş: *Castor Oil*, Ata pupa ni *Pain Killer*, Oruwọ ni *Quinine*. Lakoko arun ayọkẹlẹ (*Influenza*) mo şe bi epo pupa lasan pẹlu Ewe Asofẹiyẹjẹ ati Ewe Rere lo wo ọpọlọpọ enia san.

Ju gbogbo rẹ lọ, owo ti Kotu ngba nitori Tanwiji pọju, o yẹ ki *Nigerian Railway* din owo ori ọkọ ati owo eru wiwọn ku, o si tun tọ, ẹwẹ, ki awọn Munisipa din diẹ ku ninu orişirişi owo ti nwọn ngba lọwọ wa, ode le.

Irohin ẹjọ Imale di ig'ba-miran l'agbara Ọlọrun a ko iti gbọdọ t'ẹnu kin ọrọ na titi Onidajọ yio fi da ẹjọ na, lẹhin na la o da şẹria ọrọ fun ẹniti o ba tọ si. A mọ ẹniti o nlo isuju, a mọ ẹniti o nlo iyara.

Bi ilẹ ko ba si ni pa ewura da, o da wa loju pe ejọ ti ku, owere lo ku.

Emi ni ti nyin nitotọ,

ATARI-AJANAKU.

## BI AWỌN ONIṢỌPANNA TI ṢE NMU ENIA WỌ ISIN ORIṢA ṢỌPANNA.

[ *Lati ọwọ* Laniyọnu. ]

Nigbati awọn Onişọpanna yio ba fa ẹnikan ni ori Şọpanna, nwọn a mu egun abuke, ati egun ẹniti o ku-si ẹbu, (ẹniti şọpanna mu, ti o si ku, ni a npe ni eni-to-ku-si-ẹbu), nwọn a fẹ ewe oniruru ni okọkanlerugba, nwọn a ko gbogbo wọn sinu agbada nla kan, nwọn a ma jo wọn. Bi nwọn ti njo wọn lọwọ, nwon a sọ aye adiẹ on aye ẹiyẹle sinu agbada ewe lori ina; bi nwọn ti nṣe eyi lọwọ, nwọn a ma pe Şọpanna kikankikan, nwọn a si ma ni niran ohun buburu gbogbo ti ima şe, ati gbogbo ipa arẹ ti ima sa. Li alẹ ni nwọn ima şe eyi-bi nwọn si ti nşe e lọwọ ni kara, ilu yio ma sẹ kikan, ijo, ijẹ, imu a si wa ni itosi awọn Onişọpanna. Li afẹmọjumọ, niwọn agogo mẹta, ewe kan wa ti nwọn nja, on ni nwọn si fi nwẹ ẹniti nwọn nfẹ fari Şọpanna fun, lẹhin eyi, nwọn a fa a lori, nwọn a si mu ki o joko lori odo, nwọn a wa sin i ni gbẹrẹ larin ori rẹ, nwọn a si mu ninu ara ẹtu ti a jo ni, nwọn a si fi kun u; wọn jẹ atare, orogbo, obi, nwọn a fan a si i lori; nwọn a wa pa ẹran, kan, bi agutan ni, bi ewurẹ si ni ati adiẹ kan, nwọn a si da ẹiẹ rẹ le e lori. Nigbana ni orişa Şọpanna iwa gun ẹniti a fari fun, ki i si mọ ara rẹ mọ fun wakati diẹ. Nigbati oju rẹ ba si walẹ, nwọn a wẹ ẹ, nwọn a wa sa a li ẹfun on osun lori. Ẹran gbogbo ti a ba pa bayi, awọn babalorişa ati iyalorişa nikan ni ijẹ ẹ. Ogun ti a ti jo li ẹtu ni nini yio ma wa fi fọ ẹkọ mu ni ojojumọ, li orowurọ fun ọjọ meje. Lati igbayi lọ ni yio ti di olorişa Şọpanna, a si di ohun akunlẹ-bọ; ọrokọrọ ti o ba si sọ, abẹ lo ke e (fun wọn); bi a ti ita ni ni ori Şọpanna ni yi. Ibẹru ko jẹ ki awọn ti o mọ ọ sọ orukọ awọn ewe wọnni fun ni. Iku si ni fun olorişa-kolorişa ti o ba tumọ rẹ bayi. Awo nikan ni idi ibiti nwọn gbe nşe e, ọgberi ko gbọdọ wọ ibẹ nitori ti o jasi ohun aşiri gidigidi fun wọn.

*Nkan ti nwọn ndi jọ, li nwọn si npe li orişa Şọpanna ni iwọnyi ;—*

Iwo ẹfan nla kan, ti a kun ni osun yika, oşuşu ọwọ kan ti a kun li osun bakanna, oşuşu ọwọ keji, oni-şaşa meje; ati ẹkẹta, oni-şaşa mẹta; awọn meji ti a wi kẹhin yi ni nwọn ima fi şe ọrọ sọ wipe :—

"A ki şaşara bọ agbo,

Ẹ wi f'alejo ko lọ.

Damgboruku apa oku enia, lati ọrun ọwọ de igbonwọ, tabi titi de ejika, tabi mejeji bi a ba le ri i; agbari oku gbigbẹ, ti a wẹ mọ fonfoni, ti a si kun li osun yika; nwọn a ko gbogbo wọn sinu ọpan nla kan tabi panşuku nla ti a ti kun li osun dunra; nwọn a fi oniruru awo oyibo tabi tanganran ha a, nwọn a si fi aşọ osun we e; ati Ilẹkẹ lagidigba pẹlu ti a ti bọ osun. Niwaju eyi, ni nwọn iwa fi awọn jọlọ amọ si li apa ọtun ati li apa osi rẹ, larin awọn mejeji yi ni nwọn nfi erun egun oku enia si, nwọn a si fi omi inu jọlọ amọ mejeji ni si i ninu, pẹlu ogun asajẹ gbogbo, nwọn a bọ, nwọn a si jọrẹ si iwaju orişa Şọpanna nwọn ki isi lọ o, afi bi aje ba di aje tan, ti şẹranşẹran ba si nsẹ işẹ toto, ni nwọn ito mu iru ẹni bẹ wa siwaju orişa Şọpanna. Awọn iya ati babalorişa nwọn a ma ki iru awọn enia bẹ ni ilọ lopọlopọ ki nwon ba le sọ otitọ, şugbọn bi nwọn ba ti nsẹ sibẹsibẹ, nwọn a wa bu ninu omi inu jọlọ mẹtẹta, nwọn a fi wẹ awọn egungun to wa ninu ọpan orişa Şọpanna, nwọn a şẹ diẹ ninu egungun na fun oluwarẹ jẹ, nwọn a si bu omi rẹ diẹ si fun u mu; lẹhin ti nwọn ba ti gbe e ka orun ti o si gbona. Bi ẹni ti a wi pe o şe ọran ko ba jẹbi ọran na, ko si ohun ti işe e, a si bọ wa ile li alafia; şugbọn, bi o ba şe pe eke lo şe, yio si ku ni ọjọ keje, ko si ẹlẹbọ rẹ. Mo ri i bẹ ri ni ilu-oke; nwọn si nşe bẹ nihin pẹlu.

Nigbati awọn Onişọpanna ba nfẹ jẹun (awọn ni isa ma ko gbogbo nkan ẹniti o ku si ẹbu) ti Şọpanna ko ba si ja, ti ebi ba npa wọn, ohun gbogbo ti a wi pe nwọn ndi li orişa Şọpanna ni nwọn nmu, nwọn a wẹ wọn sinu ọpan nla kan pẹlu ohun miran, nwọn a wa mu oşuşu ọwọ oni-şaşa mẹta (ti a npe ni işaşara), lẹhin ti omi na ba ti gbona nipa fifi sinu orun pẹ, nwọn a tẹ işaşara bọ ọ, nwọn a nwan a si igun mẹrẹrin ilu, nwọn am a pe Şopanna kikankikan, nipa şişe bayi, Şọpanna a ma wa ja kakiri ni ilu.

Isin orişa yi ko si ni Ilẹ Yoruba ri; Adelu, Ọba-lọyọ, le wọn kuro ni Ọyọ ni sa kan, o si pa pupọ ninu wọn. Niwọn idunrin, awọn Ẹgba le wọn kuro ni Abẹokuta. Goloba, ologbe, nigbati o nşe ibojuto ilẹ yi, o le awọn Onişópanna kuro ni igboro Eko. Isin Orişa yi jẹ nkan ti o buru gidigidi larin awa enia, tabi ni ilu kilu, ajẹ ti o to awọn Onişọpanna ko si; ki isi şe ohun ti a ba fun li aye ni ibikibi. Şugbọn bi Şọpanna ba fẹ mu ẹnikan ti a ba ba oninure wọn kan pade, ti nwọn ba si fi omi wọn na wọn a lara, iru enia bẹ a ma san.—Iwe Irohin Eko 1889.

# R. S. JAMESON,

## Licensed Auctioneer & Appraiser,

Broad Street, LAGOS.

---

***Prompt, reliable and intelligent Service.***

---

Property real and personal sold and valuations made for Probate.

---

Low rates of Commission and immediate settlements.

## Preachers for To-morrow.

AWỌN ONIWASU ỌLA.

**ROMAN CATHOLIC (HOLY CROSS)**

Masses will be sung by Priests appointed.
Awọn Paddi ti a yan yi o ṣe Isin ni gbogbo akoko wọnyi.

(MORNING)

Masses Isin Arọ.

6.30 7.30 8.30 9.30
7.30 8.30 9.30 10.30.

(EVENING.)

Masses (Benediction) Isin Ibukun.

4.45—5.30 6.45—7.30.

ST. MICHAEL'S (Lafiaji.)

MORNING. 7 a.m.—8 a.m. 8.30 a.m.—9.30 a.m.
EVENNING. 5.45—6.30 p.m.

**ANGLICAN**

| Time. | | Preacher. |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Christ Church, | The Vicar |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 9 a.m. | St. Paul's (Breadfruit) | Right Rev. Bishop I. Oluwole |
| 6.30 p.m. | do. | Ven. Archdeacon T. A. J. Ogunbiyi |
| 9 a.m. | St. John's (Aroloya) | Rev. H. V. E Johnson |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 9 a.m. | St. Peter's (Alapako) | Rev. C. A. Ṣowunmi |
| 6.30 p.m. | | do. |
| 9 a.m. | Holy Trinity (Ebute-Ero) | Rev. S. J. Gansallo |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 9 a.m. | St. David's (Jordan) | Rev. J. A. Leigh |
| 6.30 p.m. | | do. |

**WESLEYAN**

| | | |
|---|---|---|
| 10.30 a.m. | Tinubu | Rev. E. E. Williams |
| 7 p.m. | do. | Rev. A. N. Cole |
| 10.30 a.m. | Ereko | Rev. E. K. Ajai-Ajagbe |
| 7 p.m. | do. | Rev. S. A. Pearse |
| 10.30 a.m. | Olowogbowo | Rev. A. N. Cole |
| 7 p.m. | do. | Rev. E. K. Ajai-Ajagbe |
| 10.30 a.m. | Ọbun Eko | Rev. S. A. Pearse |
| 7 p.m. | do | Bro. Cecil O. Byass |

**AFRICAN (COMMUNION)**

| | | |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Jehovah Shalom | Rev. J. F. Ogunko |
| 7 p.m. | do. | Rev. G. A. Oke |
| 9 a.m. | Erelu | Bro. I. H. Lawson |
| 7 p.m. | do. | Bro. J. T. A. White |
| 9 a.m. | Christ Church (Ebute Mẹta) | Bro. V. E. Ọlalẹyẹ |
| 6.30. p.m. | do. | Rev. J. F. Ogunko |
| 9 a.m. | Bethel | Rev. E. A. Akinyla |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 6 a.m. | Zion | Rev. N. J. D. Ṣomuji |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 10.30 a.m. | African Methodist | Bro. J. K. Coker |
| 4.30 p.m. | | Bro. E. A. Williams |

**FIRST BAPTIST CHURCH**

| | |
|---|---|
| 10.30 a.m. | Bro. O. M. Fadipẹ |
| 6.30 p.m. | Rev. J. R. Williams |
| 9 a.m. Ararọmi (Baptist) | Bro. J. F. Oṣodi |
| 6 p.m. | Bro. J. Adekoya |

**EBENEZER (BAPTIST)**

| | |
|---|---|
| 9 a.m. | Bro. E. A. Ojo |
| 6.30 p.m. | Rev. E. C. Alabi |

**BROTHERHOOD**

| | |
|---|---|
| 7.30 a.m. | Respt. Bro. S. A. Coleman Daniel. |
| 7 p.m. | Prof. Adeoye Deniga. |

**St. STEPHEN'S (EPETEDO)**

9 a.m. & 4 p.m. Very Rev. J. G. Campbell

**AHMADIA (ISLAM**

| | |
|---|---|
| 6 a.m. | Fajir Service Y. P. O. Ṣodẹinde |
| 5.30 p.m. | Open Air Service Imam K. R. Ajọṣẹ (Bamgboṣe Street.) |

**ZION CONGREGATIONAL.**

| | | |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Kakawa St. | Rev. Suptd. S. A. Coker |
| 4 p.m. | do. | do. |

**SALVATION ARMY.**

| | | |
|---|---|---|
| 10 a.m. | Glover Memorial Hall | Capt. A. A. da Costa |
| 7 p.m. | do. | Mrs. Lieut. Col. Geo. H. Souter |

**CHURCH OF GOD**

10 a.m. 22 Ọdunlami Street, Breaking Bread

7.30 p.m Open Air Service at Campbell Square, Edwin Mathew & Wm. C. T. Terrell

---

## IGBẸ L' OWO WÂ.

Bi awọn Oyinbo Oniṣowo ilẹ yi ti gba awọn Ọja wọnyi si l'ọsẹ yi ni eyi :—

EKURỌ

£15 10 0—£16 10 0 fun *ton* kan.

EPO.

£26 10 0—£28 fun *ton* kan.

COCOA.

£19 10—£21 fun *ton* kan.

---

### KANO.

ẸPA.

£14 10 0 fun *ton* kọkan.

AWỌ (*Skins and Hides.*)

Skins 1/9d fun lb kọkan.

Hides 5d fun lb kọkan.

## H. S. Freeman

(Photographer-in-Chief to His Excellency the Governor of Nigeria.)

Dealer in all kinds of Photographic Materials **Films, Post Cards, Views etc., etc, on hand.**

"Also films undertaken for development."

Satisfaction Guaranteed.

*Office*:—106, TOKUNBO STREET, LAGOS.

*Telegraphic address*:—"**FREEDE**" **LAGOS.**

P.O. Box 495.

## ERO YA WA RA.

Aṣọ siliki ti awọn Obinrin ti awọn India fọwọ se: pọun mẹrin ni a ti nta a ri, ṣugbọn a sọ ọ di pọun meji nisinsinyi: yara lọ ra tirẹ kiakia. Ẹwọn Golu ati ẹwọn ọrun ti fadaka, Ilẹkẹ fadaka, Aṣọ siliki ti awọn Indian, ọpọku-oyọku ni, tete sure lọ si ọdọ Majid Oniṣowo ara India.

4, Ondo Street, leti Church Wesleyan,
Ijero, Ebute-Mẹta.

## Chairs! Chairs!! Chairs!!!

For hire at Ilupesi Hall, Enu-owa, Lagos.

REDUCED PRICE, $1\frac{1}{2}$D. PER CHAIR, PER DAY.

Apply to the MANAGER,
J. A. OSHODI,
26, ỌBUN-EKO STREET,
LAGOS.

## AGA, AGA, AGA.

FUN YIYA NI ILUPESI, ẸNU-ỌWA, LI EKO.

OWO PỌKU NI A FI NYA NI NISISIYI, ($1\frac{1}{2}$D.) KỌBỌ KAN PẸLU ABỌ.

Lọ si ọdọ ALABOJUTO,
Ọgbẹni J. A. OSHODI,
No. 26, ITA ỌBUN-EKO,
LI EKO.




*4/6 each.*

## The Kaduna Store,

75 & 81, ODUNFA STREET,
*near Mr. A. W. Thomas's palatial residence*
ẸBUN HOUSE, LAGOS.

begs to inform all Cyclists and Motorists to *buy* always at our Store, complete spare parts and accessories for all makes of Motors, Bicycles, etc.

Established 1921, we have much pleasure to say that we have added to our STORE, Goods to the tune of £200, being expert in the repairs of Motor-cars, Bicycles and all other machinery. We specialise in the purchase of old Cars, Bicycles, Gramophones which are minutely repaired by us and in turn, sold to those unable to afford high price, at giving-away prices, viz:—£3 £4 £6 10s. respectively, according to durability and taste.

For particulars, apply to the Proprietor:—

SAM ADE: CLAY of the above address, or at 1, Macaulay Street, Lagos.

TERMS:—Cash with Orders.

## The Nigeria Commercial Training Institute.

ESTABLISHED JANUARY 1924.

The above Institute offers students an opportunity to undertake its Training in Shorthand, Typewriting and Civil Service English.

Further particulars can be obtained on application to:—

J. OLOYEDE DAVIES,
*Principal and Proprietor.*
10, Upper Offin Lane,
Lagos, Nigeria.

TERMS:—
Absolute satisfaction with results, or moneys refunded.

## A. KESSLER,

7, Labinjọ Lane. P.O. Box 459.

SAMPLE SHOW ROOM.

*Agent for* ARNOLD SCHLESINGER,
The German Trading House,
Hamburg, Germany.

SAMPLES OF ALL GOODS FOR THE AFRICAN MARKET EXHIBITED.

The Mundlos Hand and Foot Sewing Machine.

as well as the Alder Foot Sewing Machines,

*Are always obtainable from stock or for order and are ornaments for every body's house.*

**FOR SALE**

The Typewriter "Perkeo" £9. 5. 0.

Cycles

Toys

24 hours Kitchen Clocks—a good clock for a good time.

Earthenware.

Decent Wristlet Watches, sh. 8/- and sh. 4/3 each.

Carpets to make your house comfortable.

Clay Pipes, Razors, Fez Caps, Hanging Lamps, etc.

As the fire wants the wood to burn, you want my Beer to quench your thirst, therefore buy the

LION BEER (Pilsener Light) 30/- per case.

And for happy hours take a case of my requisite CHAMPAGNE per case £3. 5. 0.

## JACOB AJAYI,

*General Woollen Trader,*

has on hand Woollens in endless variety at 50, Dosunmu Street, Lagos, at

***Prices to suit everybody.***

*Call now, fortune awaits you.*

## Aworan Alarabara.

A ni Aworan oniruru fun tita lati fi ṣe ile ṣ ọṣọ. A ni ti titẹ oku Jesu, ti igbati a da a li ẹ iku, ti Onjẹ-alẹ ikẹhin. A ni ti Adam ati Efa, ti iṣẹdalẹ aiye, ti Nebuchadenezar nigbati o wa ninu ọla rẹ, ati nigbati o di ẹranko; ti obirin ti o f ọwọ mu ejo, ati ti Ọba Tatambulu.

A ni ewe Taba fun kika ta, Ọṣẹ Olọwọ—agaga; Iyọ-iyọ mbẹ lọwọ wa fun tita bi wọbu, bi o ba fẹ ẹ ni *lọnu* a le ta a fun ọ, Iṣana Alapoti fun tita, ko si bi a ti nṣe wọn. Oriṣiriṣi ọja lo wa lọwọ wa, iwọ ko le ba wa ṣowo ko ma jere tirẹ, nitori owo pọku ni a nta wọn. Owo ọja wa rọju rekọja ala. Bi o ba wa si ile-ọja wa "Ka mi, ka mi, ka mi" ni gbogbo wọn, bi o ba fẹ ja irọ wa, rin wa si ile ọja wa.

Iye owo wọn:—3d, 4d, 5d, 6d, fun ọkọkan; 2/6d, 3/-, 4/-, 5/6d fun mejila.

Ibikibi ti o ba ngbe ni *Nigeria* tabi ẹhin okun kọwe ṣowọ yala ni ede Gẹsi tabi ti Yoruba si:—

E. O. AMBẸ & BROS,
38, Moloney Bridge Street, Lagos,
(*Lẹgbẹ awọn Oniṣowo A. J. Tangalakis*),
Idumagbo, Eko.

## Ile Ita Egbogi ti Macaulay,

88, BROAD STREET.

Wabiwọsi oriṣiriṣi Egbogi lo ṣẹṣẹ de fun wa ni tita: awọn bi:—ogun Egbo oriṣiriṣi, ogun Ẹda, ogun arun aṣiri, ogun Arẹmọ, ogun Onigbameji, ogun Aran oriṣiriṣi, ogun Lakuregbe, ati awọn ogun miran ti a ko le mã to lẹsẹsẹ.

Ọpọku-ọyọku ni owo wọn, nwọn si jẹ bi idan.

Ọrẹ, ẹ lọ dan awọn Ogun wọnyi wo nibi ti a gbe nta wọn.


PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING WORKS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.